...Ilẹ̀ Iyì, Ilẹ̀ Ẹ̀yẹ



# ETO ISUNA AWA ARA WA TI IPINLE EKITI F'ODUN 2019

# ETO ISUNA AWA ARA WA TI IPINLE EKITI F'ODUN 2019

## ETO ISUNA IRAPADA

*"Ile Iyi, Ile Eye"*

# KINI ETO ISUNA?

Aba Isuna fihan ohun ti ijọba n reti lati pa wole, ohun ti o nireti lati gba wole bi iranlowo, iye ti o nireti lati fipamọ tabi ya, ati ohun ti ijọba ngbero lati na.

Aba Isuna jẹ iwe-ipamọ kan ti o ni awọn alaye nipa bi ijoba ṣe ngbero lati lo owo-ini wa ati owo-ori.

Ni eto tiwantiwa, gbogbo ara ilu ni ẹtọ lati mọ bi ijoba wa ti n lo awọn ọrọ ilu fun pipese awọn ohun amayederun.

Isuna Odun 2019 je eyi ti o bara mu, tori owo ti ijoba n gbero lati pa wole ati iye owo to ngba lero lati na je dogba-n-dogba.

# KINI ETO ISUNA AWA ARA WA?

Eto Isuna awa ara wa jẹ ẹya ti o rọrun julọ, ti kii ṣe alailẹgbẹ ti Isuna ti ijọba, ti a ṣe pataki lati ṣe alaye awọn ti o jẹ gbangba fun gbogbogbo.

Eto Isuna awa ara wa ti Ipinle Ekiti 2019 jẹ ẹya ti o ni ibamu si Iwe-aṣẹ Isuna ti Ipinle: awọn orisun ti owo ti n wa fun ijoba laarin ọdun ati ọna ti a ṣe fun lilo owo na.

Ni odun 2019, iwon isuna Ipinle Ekiti je N129,924,472,135.01.

Ninu eyi, N87,998,240,376.25 yoo wa lati apapo owo ati owo iranwo ti o wole sapo ijopa  eyi ti o fa isuna aipe-owo N41,926,231,758.76.

Isuna inawo  N41.9 bilionu ti ijoba yi o pese yi o se abojuto isuna aipe owo naa.

# ILANA TI INAWO GBOGBOGBO




Eyi ni iwon Isuna 2019. Osi je apapo owo atigbadegba ati owona lori Akanse ise.

Eyi je apapo gbogbo awọn owo ti Ipinle yi nro lati pa wole ati lati gba bi Iranlowo

Aipe Isuna le waye nigbati gbogbo eto enawo ijoba ba ga ju owo ti Ijoba ni ero lati pa  wole

Eyi ni apapo gbogbo owo ti ijoba ya labele ati okeere

Eyi ni iyato laarin aipe isuna ati gbogo owo ti Ijoba wa lati fi ropo aipe naa

# NIBO NI OWO NAA LỌ?

## ISUNA INAWO 2019




- **Owo Osu Osise**: Eyi ni owo ti Ijoba Ipinle n na lati san owo osu osisie ati awon ajemonu won miran.
- **Awon Owo Miran**: Awon owo wonyi nijoba maa n na loorekoore lori awon ise kan. Awon owo won yi ki je sisan taara fawon osise ijoba, lara won ni, owo oko ati rinrin irin ajo, nkan elo loofisi, titewe ati ipolongo, epo rira sinu ero amunawa ati beebee lo.
- **Consolidated Revenue Fund :** Eyi je ara owo isuna lati bojuto sisan owo awon osise feyinti ajemonu, gbese, sisan awon gbese pada, ele owoya nile ifowopamo, ati owo fawon to ti dipo oselu mu tele bii awon Gomina ati Igbakeji won.
- **Owo Fawon Eka Ileese Ijoba Gbogbo**: Eyi lowo ti Ijoba n fawon eka Ijoba kankan lati se awon eto ti okankan won ba ni lati se.
- **Owo Pipa Wole Labele lati Awon Ile Eko Giga**: Eyi lowo tawon Ile Eko Giga n pawole labele ti won yoo si fi se atunse awon nnkan ti won ba nilo nileewe kowa won.
- **Transfer to other Funds**: Eyi ni awon inawo nla miran ti owa fun sise ise ijoba la akoko si akoko

# PINPIN ISUNA ODUN SAWON EKA KANKAN




- Ipese enawo ti wa fun awon isori Eka Ijoba ninu Eto Isuna 2019 . Eka kankan yoo ni Ipese fun Owona Atigbadegba ati Owona lori Akanse Ise ti o je ara eya Eto Isuna Ipinle Ekiti

- Isori Eka eto Isuna 2019 ṣe afihan ohun ti ijoba nro lati ṣe ni eka kọọkan fun awọn iṣẹ ojoojumọ ati tun ṣe awọn akanse ise Eka wonyi

# PINPIN ISUNA ODUN 2019 SAWON EKA KOOKAN

**Eka Eto Oro Aje**: Lara eyi ni awon eya ijoba ti o n moju to idagbasoke ise agbe, ọrọ aje, idinku osi ati amayederun.

**Eka Igbayegbadun Awujo**: Lara eyi ni awon eya ijoba ti o n moju to idagbasoke eto eko, eto ileera, eto igbohunsafefe ati idagbasoke awujọ.

**Eka Oro Ayika**: Lara eyi ni awon eya ijoba ti o n moju to idagbasoke agbegbe ilu ati orile ede, Ilana pajawiri ati Egbin.

**Eka Isakoso**: Lara eyi ni awon eya ijoba ti o n se ofin, adajo ati awon to n se isakoso ise Ijoba Ipinle nigbagbogbo



# AWON AKANSE ISE TI O GBE PELI JULO



# NIBO NI OWO NAA YOO TI WA?

**Pipa Owo Wole:** Eyi ni apapo owo ti o wole sakoto Ijoba ni saa kan lati asunwon ijoba apapo, owo pipa wole labele.

Ni soki,Owo Pipa wole toka si owo ti Ijoba nigbagbo pe yi o gba fun awon ara Ipinle Ekiti.

Ipinle Ekiti, gẹgẹbi gbogbo awọn Ipinle miiran ni orile ede Nigeria, yoo gba ipin owo re lati owo Ijoba Apapo. Bi apeere; owo epo, afikun owo-ori ati be be lo

Awọn owo ti Ipinle Ekiti  n pa wole  ti o si n  daduro fun lilo ti ara rẹ ni a npe ni **Pipa owo wole labele.** Lara re ni awon isori owo-ori ati be be lo.

## ETO ISUNA OWO 2019: PIPA OWO WOLE ATI ORISUN OWO



# NIBO NI OWO YOO TI WA?

Owo yoo wa lati odo Ijoba Apapo (37,510,789,697.59), Owo pipa wole labele - Ile Ise Isakoso (10,817,221,596.42) ati Owo pipa awon Ile Eko Giga gbogbo (6,055,457,760.12) ati beebee lo.

Owo le wa lati apapo ayawo abele ati okeere



# PINPIN AWON OWO IRANWO

| IRANWO LABELE | ETO ISUNA OWO 2019 |
|---|---|
| **ISE AKANSE/OLURANLOWO** | **IYE NAIRA** |
| Iranwo lati SDGs CGs fun imojuto Ijoba Ibile | 600,000,000 |
| Iranwo lati SDGs CGs fun imojuto Ijoba Ipinle Ekiti | 600,000,000 |
| Iranwo lati odo Ijoba Apapo (Lori ona Ijoba Apapo ti Ijoba Ipinle Ekiti ti se) | 11,265,899,999.96 |
| Apapo Iranwo labele | 12,465,900,000 |
| **IRANWO LATI OKEERE FUN AKANSE ISE** | **IYE NAIRA** |
| SFTAS | 1,525,000,000.00 |
| Apapo Iranwo lati Okere | 1,525,000,000.00 |

Owo Iranlowo jẹ ọkan ninu awọn orisun owo ti ijọba n gba lati se awon Akanse Ise amayederun, iranlọwọ fun oro aje Ipinle, ati anfani gbogbo eniyan.

Owo Iranlowo le wa lati abeele tabi okeere. Owo na wa fun awon Akanse ise ni Ipinle.

Owo Iranlowo ki se owo yiya ti o nilo idapada ti a ba ti na fun ise ti a se to ye fun.

# ORISUN OWO: ATUPALE OWOYA

| OWOYA LATI OKEERE | ETO ISUNA OWO 2019 |
|---|---|
| AKANSE ISE/OLURANLOWO | IYE NAIRA |
| Malaria Global Funds | 3,000,000.00 |
| Nutrition & Household Food Security UNICEF Assisted | 2,500,000.00 |
| Rural Access and Agricultural Marketing Project (RAAMP) | 3,812,500,000.00 |
| FADAMA III | 528,870,000.00 |
| Community & Social Development Projects | 500,000,000.00 |
| NPI UNICEF/GAVI Assisted | 1,776,920,650.00 |
| IMCI+ Nutrition + Immunization | 80,000,000.00 |
| Ekiti State HIV/Aids Programme Development Project II | 100,000,000.00 |
| SEPIP (World Bank) | 259,896,481.05 |
| Third National Urban Water Sector Reform Project | 8,186,200,000.00 |
| IFAD Value Chain Development Sponsored Programme | 1,500,000,000.00 |
| Grant from UNICEF Assisted Program | 50,000,000.00 |
| Projects Financed under STWSS (EU) Project | 48,273,399.57 |
| YESSO (World Bank) | 746,034,880.00 |
| EU Assisted Water Supply/Sanitation Sector Reform Prog. III | 385,700,000.00 |
| IDA (Education Intervention Fund) | 264,740,000.00 |
| IDEAS | 3,812,500,000.00 |
| Projects to be Financed under STWSS (EU) Projects | 500,000,000.00 |
| UBEC Projects (FGN/World Bank) | 3,372,096,348.14 |
| **APAPO OWOYA LATI OKEERE** | **28,926,231,758.76** |

# ORISUN OWO: ATUPALE OWOYA

| OWOYA LABELE | ETO ISUNA OWO 2019 |
|---|---|
| **AKANSE ISE/OLURANLOWO** | **IYE NAIRA** |
| Eyawo labele | 13,000,000,000 |
| **APAPO OWOYA LABELE** | **13,000,000,000** |

Nitori aileto awọn owo ni Ipinle, Ijoba Ipinle Ekiti ti pese ipese lati yawo fun işuna owo re. Eyawo le je lati abeele tabi okeere. Eyawo le wa fun awon Akanse Ise ati inawo Ijoba miran

# GILOSARI

- **Pinpin owo apapo:** Eyi ni owo to je dandan lati bo sapoIjoba Ipinle lati inu asunwon Ijoba Apapo. Awon Igbimo to n ri si ipin owo naa ni Federal Account Allocation Committee (FAAC).
- **Pipa owo wole labele (IGR):** Eyi je apapo iye owoti Ijoba Ipinle kankan n pa funra re laarin saa kan.
- **VAT** - Eyi ni afikun owo-ori ti Ijoba ngba lati odo Ijoba Apapo
- **IDA -**Ajo Agbaye to n ran Ijoba lowo paapaa julo lori eto Eko
- **Draw-Down:** Eyi ni owo ti Ijoba n ya lati odo awon ajo alaanu bii Ile Ifowopamo Agbaye (World Bank)
- **SDGs Conditional Grants Schemes:** Eyi lo duro fun iranwo ti Ijoba Ipinle n gba latodo Ijoba Apapo lati se awon ise idagbasoke to ba ode oni mu.

# GILOSARI

- **Eyawo** - Ireti wa pe Ijoba Ipinle yoo ya owo laarin aba odun 2019 lati le fi se awon akanse ise to loorin.
- **Anaku Owo:** Eyi ni anaku owo odun 2018 ti a gbe wo odun 2019
- **Owo Atigbadegba :**Eyi ni ara awon owo ti Ijoba nna lati owo osu osise, enawo igbadegba owo eka akoso, ileese ati lakojo Ijoba gbogbo.
- **Owona lori Akanse Ise:** Eyi lo wa fun awon Akanse Ise idagbasoke kaakiri Ipinle yi bii Ki kole Igbalode, sise Ipopona, rira Oko ati beebeelo.

# DIE LARA AWON ISE AKANSE YIKA IPINLE YI



Pipari Gbongan Ipade ni Ado Ekiti (N700 Million)



Papako Ofurufu ni popona Ado – Ijan Ekiti (N250 Million)



Sise oju opopona tuntun to lo si Iyin Ekiti (N4 Billion)



Fifa ina monamona de agbegbe igberiko ati ilu nlanla kaakiri gbogbo Ijoba Ibile (N265 M)



Rira Ero Afunnalagara kaakiri gbogbo Ijoba Ibile wa (N200 Million)



Rira katakata ati nnkan elo ogbin kaakiri gbogbo Ijoba Ibile wa (N300 Million)



Atunse sawon oju ona to wa laarin ilu (N 110 Million)




Akoso eto eko lona lilo imo ero (N70 Million)



Idagbasoke ati atunse awon nnkan asa ati ajogunba ni Ipinle wa(N10.6 M)

# DIE LARA AWON ISE AKANSE YIKA IPINLE YI



Sise atunse awon ibi ti omi ero ti n wa ni Ipinle wa (N215 Million)



Rira awon nnkan elo imo ijinle sawon ike eko girama ni gbogbo Ijoba Ibile(N110 M)



Dida eka ti won ti n gba imo lori oro ero ayelujara sile ni Ipinle wa (N50 Million)



Kiko Ileewosan Oba Adejuyigbe ni Ado Ekiti (N2 Billion)



Igbese lati dena ekun omi agbara lawon ibi to se kokjo nipinle Ekiti(N600 Million)



Atunse oju ona Ado si Afao Ekiti (N730 Million)



Siso opopona ilu Ikere di alabala meji  (N200 Million)



Awon nnkan elo ayelujare ati gbigba ohun sile ni Ado Ekiti (N220 Million)

# DIE LARA AWON ISE AKANSE YIKA IPINLE YI

SUBEB
STATE UNIVERSAL BASIC EDUCATION BOARD

Owo lori eto eko omo alakobere
(N1.6 Billion)



Ile Eko Olukoni Agba, Ikere Ekiti
(N400 Million)




Ekiti State University, Ado Ekiti (N400 Million)



Iranlowo lori oro eka ilera ni gbogbo Ijoba Ibile (N200Million



Idagbasoke ounje eranko ati ile ifer̀anjeko(150Million)

Eko ofe fawon akeeko
(200 Million)

SCHOLARSHIPS
SCHEME



Atunse Pavilion fun orisirisi eto ni Ado Ekiti (250Million)



Atunse awon ile ikawe to ti denukole lawon ileewe Ijoba gbogbo (1.4 Billion)

# OLUBASỌRỌ

Ile Ise Ijoba to n mojuto eto Isuna ati Idagbasoke Oro Aje, Secretariat Complex V., Ado Ekiti, Ipinle Ekiti

www.ekitistate.gov.ng

Tẹlifoonu : 08032606580

Imeeli:adefolajuadeleke10@gmail.com